# Ipade *lori* Imukuro *gbogbo eka yiya awon* Obirin *soto*



United Nations

A Translation of the "Convention on the Elimination of All Forms of Discrimination Against Women" into Yoruba

# *Ọ̀rọ̀ Àkọ́sọ*

Ajọ to dale imukuro gbogbo isọri yiya awọn obinrin sọtọ, ti igbimọ ajọ isọkan awọn orilẹ-ede agbaye fọwọ si lọdun 1979 jẹ iwe aba dofin eto awọn obinrin. Iwe ipinnu naa kun fun ifaara ati ọgbọn ifadehun le lori. Iwe naa si salaye finni-finni ohun ti yiya awọn obinrin sọtọ dale, bakan naa lo tun ṣe agbekalẹ fun igbesẹ kari – orilẹ-ede ti yoo fopin si iyara-ẹni-sọtọ.

Ipade woye pe yiya-awọn obinrin sọtọ tanmọọ idayatọ, iyanikuro tabi ikanilowoko ti a n ṣe lodi si awọn eniyan nipaṣe pe wọn jẹ abo eyi to le ni atubọtan tabi ereedi isakoba tabi ifagile iduro-eeyan, anfaani tabi ẹtọ awọn obinrin lai fi ti pe wọn jẹ abilekọ ṣe, tabi lai naani ọpọ ọgbọọgba laarin ọkunrin ati obinrin, eto eda ọmọ-eeyan ati ominira ipilẹwa lẹnu eto iṣelu, ọrọ-aje amojuto, aṣa tabi ode.

Bi wọn ṣe gba awọn ipinnu naa wọle, awọn orilẹ-ede fi ara wọn ji lati dawọle aimoye igbesẹ ti yoo mu ki opin de ba yiya awọn obinrin sọtọ ni gbogbo ọna. Awọn igbesẹ naa jẹ mọ:

- Siṣe akosilẹ ilana "emi-ko-ju-e, iwọ-ko-ju-mi" laarin awọn ọkunrin ati obinri sinu ofin ile wa. Fifagile gbogbo ofin iyara-ẹni-sọtọ ati itewọgba awọn ilana to ṣe deede, ki a si sofin nipa yiya awọn obinrin sọtọ.

- Siṣe idasilẹ awọn igbimọ olugbẹjọ ati awọn ile-iṣẹ ijọba ti yoo maa ri si idaabobo awọn obinrin lọwọ iyara-ẹni-sọtọ ati,

- Lati ri si imukuro oniruuru iwa yiya awọn Obinrin sọtọ ti awọn eeyan, ẹgbẹ tabi ile iṣẹ maa n ṣe si.

Ipade tun tẹ pẹlẹmọ ọpọ ti a fi le ṣe aṣe yege ọgbọọgba laarin awọn ọkunrin ati obinrin paapaa nipa mimu ki awọn obinrin lanfani si ọna iṣelu ati iṣe-oba koda eto lati dibo ati lati gbe apoti ibo, si eto-ẹkọ ati iṣẹ siṣẹ. Awọn iko orilẹ-ede tun fẹnuko pe ki ajọ gbe igbesẹ to yẹ lọna ofin ati awọn igbesẹ akanṣe olọjọ kukuru ki awọn obinrin jẹ anfani gbogbo ẹtọ ati ominira eda-eeyan.

Ajọ yii nikan lo jẹ adehun lori ẹtọ ẹda-eeyan to fọte le eto ibisi lagbo awọn obinrin, ti o si tun fojusọ aṣa ibilẹ gẹgẹ bi agbara nla to n ṣe idari ojuşe akọ ati abo ati iba-ṣepọ agbo-ẹbi. O fase si eto awọn obinrin lati kọjọ, lati yipada ati lati di orilẹ-ede wọn ati ti ọmọ wọn mu.

Iko awọn orilẹ-ede tun fohun sọkan lati dawọle awọn igbesẹ to lodi si oniruuru iwa tita obinrin ati lilo awọn obinrin nilo kulo.

Awọn orile-ede ti wọn ti gba ipinnu naa wọle tabi ti won fara mọ igbese naa gbodọ dawọle sise awon ilana naa. Won si ni lati jabo iṣe fun ijokoo apapọ o kere tan ee-kan lodun merin lori igbese ti wọn ti dawọle lati tẹle gbogbo ilana adeun naa.

Ipade naa, to dode lọjọ keta oṣu kẹsan-an ọdun 1981 ti gba asẹ lodọ awọn omo ajo isọkan orile-ede agbaye ti adajọ orile-ede won je meji-le-laaadọjọ.

## *Ipade Lori Imukuro Gbogbo Eka Yiya Awon Obinrin Soto*

Awon Iko orile-ede ti won peju sibi ipade, yii:

Mo pe ijokoo Ajo Isokan awon orile-ede agbaye ni igbekele ninu eto eda omo-eeyan, ninu iyi ati ipeye awon eeyan ati ninu wiwa ni ogboogba laarin okunrin ati obinrin.

Mo pe Iko Akede Eto Eda Eeyan lode agbaye tewogba ilana aigba iyara eni soto laaye, ti o si gba pe gbogbo adarihunrun lo ni eto okan-koju-kan lo, ti won si dogba ni eto ati iyi nini, ati pe eni-kookan lanfaani si gbogbo eto ati ominira ti a la sile lai si iyato , yala eyi ti a fi opo ako tabi abo paala.

Woye pe awon iko awon orile-ede to wa ni agbo awujo majemu lori eto eda eeyan lagbaaye ni ojuse lati rii pe atokunrin atobinrin ni eto ogboogba lati je igbadun eto oro-aje, isamojuto, asa ati eto iselu.

Se ayewo gbogbo ipinnu agbaye ti won fenu ko le lori labe akoso Ajo Isokan awon orile-ede agbaye ati awon ajo akanse to se igbe-laruge eto ogboogba laaring okunrin ati obinrin.

Se ayewo awon ifohunlelori, ikede ati aba ti Ajo Isokan awon orile-ede agbaye tewogba ati awon akanse ajo to n se igbelaruge eto ogboogba laarin okunrin ati obinrin.

Sugbon o je ipade logun pe bi o tile je pe awon ilana ati ohun amulo won-yi wa nle, sibe asa yiya awon obinrin soto tubo n peleke sii ni.

Ipade seranti pe yiya awon obinrin soto tako awon ilana eto eda ati ibowo fun eeyan, o si je idena fun awon obinrin lati lowo si eto iselu, isamojuto ilu, oro-aje, igbeaye lawon orile-ede won ni ilana eto-ko-ju-eto lo. Bakan naa, o tun je ihalorun fun idagbasoke anikun awujo ati ti agbo ebi. O tun je ki idagbasoke to kun lori okun awon obinrin lenu ise lawon orile-ede won soro lati dawole, ati ti eda eniyan.

Ipade kominu pe ni aaye ise, awon obinrin ni ki i ni anfaani si onje eto ilera, igbeko, idanilekoo ati awon anfaani to ro mo ise-sise ati awon ilo miiran.

O da ipade loju pe idasile eto oro-aje titun lagbaaye ti o faaye gba idogba ati ododo a kopa to ye kooro ninu sise igbelaruge idogba laarin okunrin ati obinrin.

Ipade tẹ pelẹ mo on pe iyokuro eleyamẹya, gbogbo ipele iyara-ẹni-sọto tori awo, tori eya, imunisin, ijegaba-lori-eni, iwa ipa, fifi ipa dosi ile eni, idari eni lona aito ati atojubọ si oro abele orile-ede miiran se pataki si ijanfaani eto okunrin ati obinrin to kun oju osunwon.

O tun gba pe sise imulokun alaafia ati aabo agbaye, rire kookoo ode agbaye nle, ifọwọsowọpọ laarin awọn orile-ede lai fi ilana orọaje ati isamojuto wọn ṣe, titu gbogbo ohun ija ogun, paapaa julọ, ohun ọse alagbara nuclear labẹ idari agbaye to muna doko, titewọgba awọn ilana idajọ ododo, idọgba ati anfaani to wa ninu ibara eni sepọ laarin awọn orile-ede, mimo riri etọ awon eeyan to wa labẹ isakoso awọn ijoba ajeji ati dido si ile to fe da se akoso ati ominira ara rẹ pelu-pẹlu ibọwọ fun orile-ede olominira, aaye ile onikaluku, gbogbo iwọnyi a ṣe igbelaruge ilọsiwaju eto isamojuto ati idagbasoke, bee ni yoo kopa ninu aṣeyege idọgba to kun laarin okunrin ati obinrin.

O da ipade loju pe idagbasoke to kun to si pe ni orile-ede, iṣamojuto ode-agbaye ati atọkun alaafia, n fe ifọwọsowọpo elekun-rere, ti obinrin ati ọkunrin, ti won letoo logbọọgba ni gbogbo ona..

Mimọ riri ojuṣe pataki ti awon obinrin n ko ninu eto iṣamojuto agbo-ẹbi ati idagbasoke awujọ, ti a ko i tii ṣe aṣeyege re tan, ipa pataki iya ati ojuse iya ati baba lagbo-ẹbi ati ninu tito awon ọmọde, pẹlupẹlu, pe ojuṣe awọn obinrin ninu eto omobibi ko gbodọ di osuwon iyara-eni-soto, sugbọn tito awon omode gbodọ je ajumopin ojuse laarin okunrin ati obinrin ati awujo lapapọ.

Mimọ daju pe ayipada ojuse ti a mo awon ọkunrin mọ ati pelu ojuse awon obinrin lawujo ati lagbo-ebi, se pataki lati le se aseyege idọgba to kunju osuwọn laarin awọn ọkunrin ati obinrin.

Pipinnu lati dawọle awọn igbese ti a la sile ninu ikede imukuro iyara-eni-sọtọ to tako awon obinrin ati pelu, lati tewogba awọn ilana to wulo fun siṣe imukuro iru iyara-eni-sọto bee ni oniruuru ona.

Ipade ti fohun so-kan lori awọn nnkan wonyi:

## *Apa Kinni*

### *Ipinnu Kinni*

Ni ti tori ajọ ti isisiiyi, ẹyọ oro yii – “Iyara-eni-sọtọ to tako awọn obinrin”, a tumo si iyatọ, iyọkuro tabi ote ti a le fi lele nitori pe enikan je okunrin tabi o je obinrin, ni atubotan igbegidina tabi ifagile ikanikun, ijegbadun tabi, bi awon obinrin

ṣe lè lo agbara, lai fi ipo tabi aaye ti wọn wa ṣe, ṣugbọn ni osuwọn idọgba laarin ọkunrin ati obinrin, ni iha ti ẹtọ ẹda-eeyan, ominira ti iselu, ọrọ-aje, isamojuto, asa ibilẹ tabi iha miiran.

*Ipinnu Keji*

Ikọ awọn orile-ede bẹnu àtẹ lu iwa yiya awọn obinrin sọtọ ni gbogbo ọna wọn si fohun ṣokan lati lepa, ni gbogbo ọna to ba tọ, lai fàkókò sòfò, ilana pipàna yiya awọn obinrin sọtọ, ati lati dawọle:

(a) Siṣe akọsilẹ ilana idọgba laarin awọn ọkunrin ati obinrin sinu iwe akọsilẹ wọn, lorilẹ-ede tabi sinu iwe-ofin miiran ti a kò ba i ti i se akọsilẹ bẹẹ; lati rii pe a dawọle igbésè aseyege nilana ofin ati awọn ọna miiran.

(b) Lati tẹwọgba awọn ilana ofin ati awọn igbese miiran, bi itakéte si, nibi tó ba yẹ, sisofin lòdì si gbogbo ọna ti a n gbà ya awọn obinrin sọtọ.

(d) Lati ṣe idásile ètò àabò lọna ofin lori awọn ètọ obinrin ni ọgbọọgba si ti awọn ọkunrin ati lati ri i daju pe awọn alaṣe ile-iṣe ọba ati ẹka gbogbo dawọle igbésè to ba ètò yii mu.

(e) Lati yẹra fun iwa tabi iṣe yiya awọn obinrin sọtọ ati lati ri i pe awọn alaṣẹ iṣẹ-ọba ati ẹka gbogbo húwà ni ibamu si ojuṣe yii.

(e) Lati dawọle awọn igbése tó tọna ti a lè fi dèna yiya awọn obinrin sọtọ ati lati ri i daju pe awọn alase-ọba ati ẹka gbogbo huwa ni ibamu si ojuse yii.

(c) Lati dawọle awọn igbése to tọna ni ti ilana ofin, lati se àtuntò tabi lati fagilé awọn ofin to ti wa tẹlẹ, ilana, aṣa ati ọna-àgbàse-Iṣe eyi to sọ ni di eni ìyà sòtò lagbò àwon obinrin.

(d) Lati fagile, gbogbo ilana ijiya ti orile-ede to jẹ iyanisọtọ fun awon obinrin.

*Ipinnu Kẹta*

Awọn Ajọ Orilẹ-ede a tewogba gbogbo ilana to yẹ, ni pataki ni iha ti ètò

iselu, isamojuto, oro-aje ati asa obinrin, ni ilana akosile ofin, lati rii pe a seto idagbasoke ati itesiwaju to kún fun awon obinrin, ki won le ni idaniloju agbara lati janfaani gbogbo eto eda-eeyan ati ominira ni-ilana ogboogba bi i ti awon ọkunrin.

### *Ipinnu Kẹrin*

Pe ki awon Ajo orile-ede tewogba awon ilana olojo-kukuru to je akanse eyi to dale iyakankan idogba laarin awon okunrin ati obinrin, ki a si ma se ka iru awon ilana bee si iyara-eni-soto, eyi to wa ninu akosile ajo. Sugbon ko ni i ni isamojuto alaidogba tabi osuwon to da yato. Awon igbese won-yi ko nii wulo mo ti awon erongba anfaani idogba ati iseto to yẹ ba ti kese jari,

(2) Pe awọn Ajo orile-ede a tewogba awon igbese akanse, bi i ti awon ilana to wa ninu akosile ajo naa, eyi to dale idaabobo awon abiyamo lai ka a si iyara-eni-soto.

### *Ipinnu Karun-un*

Awon Orilẹ-ede a tewo-gba awon ilana to ye:

(a) Lati se atunse si ihuwasi lona aṣa ati isamojuto awon okunrin ati obinrin, lati le se ase-yege imu-kuro ininisinu ati awon ise, eyi to fi ijunilo tabi aito-ni se opo lagbo eya mejeeji tabi lori ojuse ti a ti fojuda funraawa fun awon ọkunrin ati obinrin.

(b) Lati ri i daju pe eko agbo-ebi dale nini imo ati oye awon abiyamo ati ojuṣe ajumọsepo laarin okunrin ati obinrin, ninu akitiyan tito awon omode sona, ati etọ idagbasoke won, ki a si mo pe isetoju awon omo won se pataki pupo ni gbogbo ona.

### *Ipinnu Kefa*

Awon Ajo orile-ede ni lati dawole awon bi i ti akosile ofin, lati te gbogbo ona ti a n gba fi obin obinrin fun ise asewo sinu iwe.

## *Apa Keji*

### *Ipinnu Keje*

Awọn Ajo Orile-ede a dawole ilana lati yo iwa yiya awon obinrin soto kuro, ni iha ti eto iselu ati ise oba lorile-ede yii ati ni pataki, lati ri i daju pe awon obinrin ni eto ati idogba bi i ti awon okunrin:

(a) Lati dibo lasiko gbogbo eto idibo ati fifi ibo yanju koko oro, ki awon obinrin naa si le gbe apoti ibo ni gbogbo ibo ti a ba seto lorile-ede.

(b) Lati kopa ninu agbekale ilana ijoba ati idawole re, lati bo sipo ati lati se ojuse eni ti o wa nipo ni gbogbo ipele isakoso ijoba.

(c) Lati kopa ninu gbogbo ajo ti ki i se ti ijoba ati gbogbo egbe to je mo ti eto ise ona ati iselu orile-ede.

***Ipinnu Kejo***

Awon Ajo orile-ede a dawole awon igbese to ye lati ri i pe awon obinrin wa ni idogba si awon okunrin, ati lai si iyara eni-soto, ni anfaani lati soju ijoba ni ode agbaye ati lati kopa ninu gbogbo ise awon ajo agbaye.

***Ipinnu Kesan-an***

(1) Awon Ajo orile-ede a fun awon obinrin ni eto ogboogba bi i ti awon okunrin lati beere fun, lati yi pada tabi lati di anfaani omo onile mu. Won gbodo ri i daju, ni pataki, pe igbeyawo pelu ajeji tabi yiyi orile-ede eni pada nipase oko lasiko igbeyawo ko so iyawo di omo orile-ede miiran, ko so iyawo di eni ti ko ni ipinle mo tabi ki a fi ipa so o di omo orile-ede ti oko re i se.

(2) Awon Ajo orile-ede gbodo fun awon obinrin ni eto to dogba si ti awon okunrin nipase omo orile-ede ti awon omo won je.

## *Apa Keta*

***Ipinnu Kewaa***

Awon Ajo orile-ede a gbe igbese to ye lati mu kuro, iwa yiya awon obinrin soto, ki won le ni eto ogboogba pelu awon okunrin ninu eto eko ati ni pataki, lati rii pe awon okunrin ni eto to dogba pelu awon obinrin ni iha:

(a) Ilana kan naa lenu ise sise ati itonisona lenu ise-owo, ki won le lanfaani si eko ati si aseyege nini iwe-eri lawon ile-eko oniruuru ipele lawon agbegbe igberiko ati awon ilu nla nla. Idogba yii gbodo fese mule lawon ipele inu ile, gbogbo-gboo, ise owo, ikosemose ati ile ekose owo giga ati oniruuru ipele idanilekoo ise owo.

(b) Aaye si isori ise tabi ilana igbeko kan naa, idanwo kan naa, awon Oluko ti won ni iwe-eri kan naa ati osunwon kan naa ati ayika Ile-eko ati ohun eelo igbeko to koju owo.

(d) Imukuro gbogbo ojuṣe ọkunrin ati obinrin to ti di mọọli si wa lara ni gbogbo ipele ekọ, nipa sise isiri ile-iwe ti awon okunrin ati obinrin a maa kawe po ati awon inife seto eko miiran to le se iranwo lati se aseyege erongba yii, ati ni pataki, nipa siṣe agbeyewo awọn iwe-kika, awọn eto ile-iwe ati ṣise amulo ọgbọn agbakoni-lẹkoo.

(e) Anfaani kan- naa fun ọkunrin ati obinrin ki wọn le jẹ igbadun eto ẹko-ofe ati awọn igbekoọ miiran.

(e) Anfaani kan naa si awọn eto igbeko onitesiwaju, bi i ti ẹko awọn agba, eto igbeko to ye kooro, paapaa julo awọn eto ẹko to dale didi alafo eko to wa laarin okunrin ati obinrin ku bi o ti ye.

(f) Ẹdinku iye awon akekọobinrin to n fidi rẹmi ati iseto awọn etọ iṣe fun awọn ọmobinrin ati awon abileko ti won fi ile-iwe sile lairotele.

(g ) Ipese anfaani kan naa lati kopa to ye kooro ninu ere idaraya ati ẹko nipa ere amara lokun

(gb ) Aaye si awọn iroyin nipa eko lati le se iranwo eto ilera ati imarale awọn agbo-ebi; isan iroyin ati imoran lori ilana fifi eto si ebi.

*Ipinnu Kōkanla*

1. Awọn Ajọ orile-ede a dawole awọn ilana to ye lati mu kuro lorii yiya awọn obinrin soto lenu igbani-senu-ise lati le ri i daju pe idogba wa fun awon ọkunrin ati obinrin lori eto, ni pataki:

(a) Ẹtọ lati siṣẹ gegẹ bi eto ti gbogbo eeyan ni lati sise.

(b) Eto si irufe anfaani iṣe-ṣise, lilo awọn osunwọn idajọ kan naa lenu gbigbani ṣenu ise.

(d ) Ẹtọ si yiyan irufẹ ise tabi ikosemosẹ to wu ni, ẹto si igbega, aabo lẹnu-ise, Ajẹmọnu ati ilana igbani-ṣise ati eto si gbigba idani-lẹkoo iṣe-owo atunkọ, siṣe omo ekose, idanilekoo agba lori ise-owo ati idanilekoo atigba-degba.

(e ) Eto si iye owó-oṣu to dọgba, ajẹmọnu iseto fun ni lọgbọọgba lori iṣe to ni iye kan naa lori, idọgba ninu siseeto igbeléwọn iṣẹ to peye.

(e ) Ẹto si aabo lenu ise, paapa julọ, nipa ifeyinti, airisẹse, ailera, ogbó ati awọn ilana miiran si iṣẹ ati etọ si owó isimi lẹnu iṣẹ.

(f ) Ẹtọ si idaabobo ilera ati si aabo lẹnu iṣe – ririi pe obinrin to n ṣiṣẹ kò padanu etó ọmọ bibi tabi anfaani ibisi.

2. Ti a ba fẹẹ dena yiya awọn obinrin sọto, lori ipele igbeýawo tabi wiwa ni ipo iloyun, ati lati ri i pe won letọ to muna doko lenu ise, awon Ajo orile-ede gbọdo dawole awon ilana tó ye:

(a) Ki won fofinde yiyo-ni-kuro lẹnu iṣe tori ipo iloyun tabi nitori isimi lori oyun-nini ati yiya awon obinrin soto lori idaniduro tori pe obinrin loko.
Igbése yii wa lowo irufe ijiya tó ro mo on.

(b) Lati ṣe idasilẹ isimi lákooko iloyun pẹlu sisan owó tabi siseetò awọn anfaani tó joju lai pàdanu ise ipo tabi awọn eto tò wa fun won.

(d ) Làti se isiri ipèse awọn ilana aṣeranwo ki awọn òbi le kó ojuṣe inu agbo-ẹbi pọ mọ ojuṣe enu-iṣẹ ati ilowósi ojuṣe ode, paapaa, nipa-ṣẹ igbélarugẹ idasile ati eto idagbasokè awon ohun kòseemánii tó wa fun iṣetọju awon omode lòpò yanturu.

(e ) Lati pese akanṣe aabo fun awọn obinrin lasiko iloyun lawon enu iṣẹ to le se à-kòba ipo iloyun won.

3. Akọsilẹ ofin to n daabobo-ni to jẹ mo awọn koko-oro to wà ninu akọsilẹ yii, yoo maa di agbeyẹwo lati igba-degba nitori imọ ijinlẹ sayensi ati imo ero-gbogbonṣe to gbode, bee ni a oo ma yi i po, muu kùro tabi fi kun un bi o ba se yẹ.

*Ipinnu Kejila*

1. Awon Ajo orile-ede yoo gbe awon igbeṣẹ lati se imukuro yiya awon obinrin soto ni iha eto ilera ki won le nì anfaani si ipese eto-ilera ni ogboogba bii ti awon okunrin, ati eyi to jẹ mo ifeto-somo-bibi.

2. Lai fi ipese to wa ni ipinro kinni itoka yii ṣe, awọn Ajọ orilẹ-ede yoo rii daju pe awọn obinrin ni ipese to tọ si wọn ni iha iloyun, wiwa-ninu-ilé ati nigba ti won ba bimọ tan, ki won si maa ri itoju ofe gba, ati ounje-to pe lasiko iloyun ati ibimo.

*Ipinnu Kẹtalá*

Awọn Ajọ orilẹ-ede yoo dawọle awọn ilana ti yoo fa imukúro yiya awọn obinrin sotọ ni awọn isori idawole eda bi i oro-aje, igbé-aye ọgbọogba pelu awọn ọkunrin, ki won si ni eto to dọgba, ni pataki;

(a) Ẹto si anfaani tabi ajemonu ẹbi.

(b) Ẹto si ẹyawo ni ilé-ifowopamọ, owó ikọlé, ati awọn eto ẹyawó miiran.

(c) Eto lati kopa ninu awọn ere inaju ere idaraya ati awọn ilana igbé-aye tó kù.

*Ipinnu Kẹrinla*

1. Awọn ajo orile-ede gbọdọ fiyede irufẹ isoro ti awọn obinrin igberiko n dojukọ ati ipa nlanla ti awọn obinrin igberiko ń ko ninu akitiyan mimu agbo ẹbi wa laaye, iṣẹ wọn ninu awon iha ti ko la owó lọ lenu orọ-aje wa; won gbodo gbe igbesẹ ti yoo mu ki a dawọle awọn ilana tó wa ninu akosilẹ, ajọ nla yii bi o se wa fun awon obinrin agbegbe igberiko.

2. Awọn ajọ orilẹ-ede yoo dawọle awọn igbesẹ ti yoo mu iwa yiya awọn obinrin sọto kuro lagbegbe igberiko, ki wọn baa le kopa ki wọn si janfaani ninu ètò idagbasoke igberiko lọgbọogba pelu awon ọkunrin ati ni pataki, lati ri i pe awon obinrin igberiko ni ẹtọ:

(a) Lati kopa ninu imugbooro ati idawole ilana idagbasoke ni gbogbo ipele.

(b) Ki wọn ni anfaani si eto ilera to pe, iroyin, igbani-nimoran, ati ipese anfaani si ilaniloye lori ifetosọmọbibi.

(d ) Lati janfaani ninu gbogbo eto isamọjuto ni taara.

(e ) Lati gba gbogbo idanilekoo oniruuru ati eko, yala ni ile-iwe tabi agbeleka, kikobi-ara si eka ati nini anfaani si awon ise imugbooro agbegbe ki ijafafa won lenu ise-owo le po si i.

(e ) Lati seto iko iran-ra-eni-lowo ati egbe alajoda ki won le ni aaye si awon anfaani oro-aje nipase ise sise tabi idasesile funra-eni.

(f ) Lati lowo si gbogbo akitiyan agbegbe.

(g ) Lati ni aaye si eto iyawo, isẹ ohun-ogbin, awon eto itaja, imo-ero gbogbo-n-se to ye fun won ati siseto nipa ile ati sise afiwo lori ile.

(gb ) Lati je igbadun igbe-aye to peye, paapaa julọ ni iha ile gbigbe, imototo, ina-oba, ipese omi-ero, igbokegbodo ati eto ibara-eni soro.

## *Apa Kerin*

### *Ipinnu Keedogun*

1. Iko awon orile-ede ma fi awon obinrin si ipo kan naa pelu awon okunrin labe ofin.

2. Ni ibikibi ni gbogbo awon obinrin ti ni eto lori oro ejo keke-ke to le jeyo labe ofin gege bi o ti se wa fun awon okunrin pelu anfaani kan naa lori eto igbejo. Ni pataki, won gbodo fun awon obinrin ni eto kan naa lati gba ise se ati lati ni ase lori ohun ini. Bakan naa ni won yo tun ni eto kan naa lori igbese yowu ti o le waye ni awon ile ejo ati igbimo oluwadi.

3. Iko awon orile-ede tun fenu-ko pe gbogbo ohun kohun labe ofin ti o je idiwo fun eto awon obinrin, ti di otubante.

4. Awon orile-ede maa ri daju pe eto kan naa ni awon okunrin ati obinrin ni labe ofin ti o fun won ni ominira yiyan fanda omo eniyan ati lati yan aaye ibugbe pelu abinibi eni.

*Ipinnu Kerin-din-logun*

Iko awon orile-ede maa gbe gbogbo igbese ti o to lati fopin si iwa yiya awon obinrin soto lorii gbogbo oro ti o ba jemo igbeyawo ati oro ebi paapaa julo won a rii daju pe gbogbo eto yowu to ba n jeyo je dogba-n-dogba.

(a) Eto kan naa lati se igbeyawo.

(b) Eto kan naa lati yan aayo aya tabi oko ti won ba fe lati inu wa.

(d) Eto kan naa ati ojuse lasiko igbeyawo ati ituka tabi iyapa.

(c) Eto kan naa lati jijo pinnu atokan wa lori oro ati ojuse fifi eto si omo bibi iyen iye omo ti won fe bi. Ki won si tun ni anfaani ilani-loye, imo eko ati gbogbo ona ti won fi le ni awon eto wonyi.

(d) Eto ati ojuse kan naa lorii gbigba omo to itoju, aabo ati siso omo domo eni tabi labe awon ilana yowu ti oro yi le jeyo labe ofin. Bi o ti le wu ki o je, eto awon omo lo se pataki ju.

(e) Eto kan naa gege bi oko ati bi iyawo pelu eto lati yan oruko ti o wuni fun ebi eni, ise ti o wuni lati se ati ise oojo eni.

2. Ifini loko ati igbeyawo omo ko gbodo ni atako labe ofin bee si ni gbogbo igbese to ba ye labe ilana ofin gbodo fi yeni iye ojo ori ki igbeyawo kan to waye labe akosile iwe igbeyawo ki o je dandan.

## *Apa Karun-un*

*Ipinnu Keta din-logun*

1. Fun itesiwaju ninu abajade ipade yi, idasile igbimo kan maa waye lori ifopin si yiya obinrin soto (eyi ti a o maa pe ni igbimo) ninu e, ti abajade yi ba bere si sise yo je meji-din-logun. Ti ipade iko awon orile-ede marun-din-logoji ba fonte tee ninu eyi ti a o ti ri awon amoye meta-le-logun ti won ja fafa ninu ise ipade yi. Iko awon orile-ede ni yo yan awon amoye yi laarin ara won lori bi eni kookan won ba se te won si.

2. Idibo bonkele ni a o fi yan awon omo igbimo lara akojopo oruko ti iko awon orile-ede ba yan. Orile-ede kookan le yan enikan laarin ara won.

3. Idibo akoko maa waye laarin oṣu mẹfa lẹhin ti abajade ipade yi ba ti bere si ni sise. O kere tan, ni osu meta ki idibo to waye, akọwe agba fun Ajo Isokan Agbaye maa kọ iwe si iko awọn orile-ede pe ki wọn fi oruko eniti won ba yan ranṣẹ laarin osu meji. Akọwe agba a wa se akojọpọ orukọ awọn ti won yan ni siṣẹ n tele bi wọn se yan wọn lati orilẹ-ede kookan ki o to gbee siwaju iko awon orile-ede.

4. Idibo yiyan awọn ọmo igbimọ yi, maa waye ni Olu ile-iṣẹ Ajọ Isokan Agbaye nibi ipade awon orile-ede ti akọwe agba maa pe. Nibi ipade yi, ida-meji ninu meta ese awon orilẹ-ede lo gbọdọ pe, ki ipade to le waye. Gbogbo awọn ti won ba ni ibo to poju ti ọpọ lara awọn asoju orile-ede ba dibo fun ni won yo dibo yan sinu igbimo yi gege bi omo egbe.

5. Gbogbo awon omo egbe ti won ba dibo yan maa lo odun merin gbako ninu igbimo naa. Sugbon sa, asiko awon mesan ninu won ti won ba fi ibo akọko yan maa pari lehin odun meji. Ni kiamosa lehin idibo akoko, alaga igbimo maa gbe oruko awon omo egbe mesan ninu igbimo naa jade lorii tita bii tete.

6. Idibo yiyan afikun omo egbe marun maa waye labe ilana to wa ninu ese keji, iketa ati ikerin ipinnu yi lorii agbejade karun-din-logoji. Ọdun meji ni saa ti meji lara awon ipinnu omo egbe ti won yan yi maa lo. Alaga igbimo ni yo yan awon omo egbe meji naa bi eni ta tete.

7. Fun yiyan omo igbimo si aaye to ba sofo, orilẹ-ede ti ko ni amoye ninu awon omo egbe igbimo ni yo yan amoye miran lati orile-ede re bi igbimo ba fowọ sii.

8. Pelu ase ile igbimo gbogbo gboo awon omo igbimo maa gba awon ohun atilehin tabi iranlowo lowo Ajo Isokan Agbaye lorii bi ile igbimo gbogbo-gboo ba se pinnu lori e si nipa mimo pataki ati ojuse igbimo yi.

9. Akowe agba Ajo Isokan Agbaye maa pese awon osise to ye ati awon ohun eelo ti o ba to fun aseyori ojuse igbimo yi.

*Ipinnu Keji-din-logun*

1. Iko awon orile-ede gba lati gbe abajade lori ilana isofin, idajo, akoso ati awon ona miran ti won tun fowosi lati jeki ifenuko ipade naa muna-doko fun akowe agba Ajo Isokan Agbaye ati itesiwaju to ba jeyo.

   (a) Laarin odun kan ti won ba muse se lorile ede kan ati

(b) Lehin eyi, o kere tan lodun kerin sira won, nigba yowu ti igbimo ba beere fun un.

2. Agbejade abo lori eto yii le tokasi orisirisi ohunkohun to le jeyo pelu awon isoro ti o le mu ifasehin ba amuse awon ilana wonyi labe agbejade ipade yi.

*Ipinnu Kokan-din-logun*

1. Igbimo yoo se agbejade awon ilana ofin amuse se fun ara won.
2. Igbimo a yan awon loga-loga fun ise won fun odun meji.

*Ipinnu Ogun*

1. Igbimo yii a maa joko ipade fun ose meji o kere tan lodoodun lati le se agbeyewo abo atejade ojuse eto ise yi gege bi o ti se wa ninu ipinnu keji-din-logun ijoko ipade awon orile-ede.

2. Ipade igbimo maa waye ni Olu ile-ise Ajo Isokan Agbaye tabi ni ibo miran ti igbimo yi ba fe.

*Ipinnu Kokan-le-logun*

1. Igbimo yii maa gbe atejade orisirisi akitiyan won, ojuse ati aba lorisirisi to jeyo lati odo awon orile-ede to wa ninu ipade siwaju igbimo gbogbo-gboo Ajo Isokan Agbaye latowo igbimo alabe sekele lori eto oro aje ati awon ohun amuludun.

2. Akowe agba maa jabo ise igbimo yi fun awon alakoso lori oro ipo awon obinrin.

*Ipinnu Keji-le-logun*

Gbogbo awon akanle yan asoju ni won ni anfaani lati soju nibi ijoko lori Agbeyewo atejade iko ipade awon orile-ede lori awon koko ojuse ise won. Igbimo yii tun le kesi awon asoju yi lati jabo lori aseyori awon koko ise ti o kan won lati se.

*Apa Kefa*

*Ipinnu Keta-le-logun*

Ko si ohun kohun kan ti o le tako ilana yowu to muna doko fun aseyori lori eto ori ko jori fun okunrin ati obinrin ti o le jeyo:

(a) Labẹ ilana ofin orilẹ-ede kan tabi.

(b) Ninu ilana aṣẹ ipade ikọwọ bọwe adehun tabi ifẹnuko ti o ba wa fun orilẹ-ede na.

### *Ipinnu Kẹrin-le-logun*

Ikọ awọn orilẹ-ede gbà lati fọwọ si gbogbo igbése ti o ba jẹyọ ninu apapọ ajọ orilẹ-ede ti ó le jeki gbogbo igbesẹ wọn lori awọn ètó ti ipade gbe jade yorisi rere.

### *Ipinnu Keẹ-dọgbọn*

1. Gbogbo awọn orilẹ-ede ni yo fọwọ si agbejade ipade yi.

2. Akọwe agba Ajọ Isọkan Agbaye ni agbateru ojuṣe ipade yi.

3. Fifọwo si agbejade ipade yi maa waye, eyi ti wọn yo gbe siwaju Akọwe Agba Ajọ Isọkan Agbaye.

4. Gbogbo orilẹ-ede lo ni ètọ lori agbejade ipade yi. Ṣugbọn Akọwe Agba Ajọ Isọkan Agbaye ni olu-dâabò lori ètò yi.

### *Ipinnu Kẹrin-din-lọgbọn*

1. Ki atunṣe tabi ayẹwo kan-kan tó lè waye lori agbéjade ipade ikọ awọn orilẹ-ede, nigba yowu, orilẹ-ede kan a kọ iwe lori ẹ si akowe agba Ajọ Isọkan Agbaye.
2. Ijóko Ipade gbogbo-gboo Ajọ Isokan Agbaye ni o lè pinnu lori igbẹsẹ to ba yẹ fun iru ibeere beè.

### *Ipinnu Kẹta-din-lọgbọn*

1. Abajade ipade ikọ awọn orilẹ-ede maa bẹrẹ si ni ṣiṣẹ lọgbọnjọ lẹhin ọjọ ti akọwe agba Ajọ Isọkan agbaye ba gbaa wọle labẹ òté ogun.

2. Fun orilẹ-ede kọọkan ti o ba fọwọ si abajade ipade yi lẹhin to ti wọnu iwe ofin ote ogun, abajade naa a bẹrẹ si ni ṣiṣẹ ni ọgbọnjọ lẹhin ti wọn ti gbe kalẹ fun ifọwosi.

### *Ipinnu Keji-din-logbon*

1. Akowe agba Ajo Isokan Agbaye maa se atewọgba akiyesi ti orile-ede kan ba gbe jade, ki o si pin kaakiri gbogbo awon orile-ede.

2. Ko si aaye fun akiyesi ti o tako idi pataki fun ijoko ipade iko awon orile-ede.

3. Orile-ede kan lè pe akiyesi re pada nigba kii gba nipa kiko iwe si akowe agba Ajọ Isọkan Agbaye, ṣugbon akowe agba gbọdọ fi to gbogbo awọn orilẹ-ede leti. Iru ibeere bẹẹ maa bẹrẹ si ni sisẹ ni ojọ ti iwe ibeere yi ba wọle.

*Ipinnu Kokandinlọgbọn*

1. Ede-ai-yede to ba wa laarin orile-ede meji tabi ju bẹẹ lọ to dale itumọ tabi isamulo awọn ipinnu ajọ yii ti dunaa dura ko le pana ede aiyede bẹẹ, yio de iwaju ile ejọ ti okan ninu awọn orilẹ-ede bẹẹ ba fe ki oro wọn de iwaju ile ejọ. Ti awon orile-ede naa ko ba le fenu ko lori idajọ igbimo olugbejọ, lẹyin osu mefa ti orile-ede naa gbe ejọ de odọ igbimo, okan ninu won le gbe ede-ai-yede won lo sodo ile-ejọ Agbaye ni ibamu si ilana ile-ejọ naa.

2. Ajọ orilẹ-ede kookan le yo ara re kuro ninu asẹ to wa ni ipinrọ kinni ipinnu yii ni akoko ifọwosi tabi igbawọle ipade ajọ yii. Awọn ajọ orilẹ-ede to ku naa lè ko asẹ to wa ni ipinro naa, fun orile-ede to ba ni ikun-sinu nipa asẹ naa.

3. Ajo orilẹ-ede to ba ni ikun-sinu ni ibamu si ipinrọ keji ipinnu yii le kowẹ ranṣẹ si akowe-agba ajọ isokan awọn orile-ede agbaye pe oun ko lodi si ipinnu naa mọ.

*Ipinnu Ọgbọn*

Ipinnu ajọ yii to wa ni ede Larubawa, ede ilẹ China, ede Gẹesi, Faranse, ede Rosia (Russia) ati ede payọn (spanish) ti wọn jẹ ojulowo, yio wa ni odọ akowe-agba ajọ isokan awọn orile-ede agbaye.

# *Yiya Obirin Sọ́tọ̀ Lódì Si Ìlànà Ẹ̀tọ́ Ọlọ́gbọọgba Ati Ìbọ̀wọ̀ Fún Ipo Ọmọ Ẹ̀dá*

Published by the United Nations Informations Centre
17 Kingsway Road, Ikoyi, Lagos, Nigeria.
DPI / 993 / Rev. 1 / WOM - December 1999